# IROHIN YORUBA

Ẹ̀yin Oro Wa—"IWAJU L'OPA ẸBITI NRE SI"

AWỌN ONISOWO PANLA D'EGBE SILE L'EKO : AWỌN ỌLỌSA NSORO NI ILU KANO

VOL. VIII NO. 4— IBADAN, MONDAY MARCH 9, 1953 OWO IWE IROHIN YORUBA — KOBO KAN (1d)



Aworan oke yi ni ti Ọgbẹni Don Llempart Anlat ti iṣe Asoju Awọn Ẹgbẹ Onisowo Fernando Poo ati Awọn Ẹgbẹ Ọnigẹdu Rio Muni. Oun ni o na ọwọ si Ọgbẹni Ọlọla S. L. Akintola (Minister of Labour) lati Calabar lọ si Fernando Poo nigbati Ọlọla na lọ ṣe ibẹwo ilu abẹ Ijọba Spanish ni aipẹ yi, ati ilu Calabar ni o fi ijoko si.

## Awon Onisowo Panla D'egbe Sile

Ni aipẹ yi ni awọn onisowo ẹja panla tabi ẹja pilipili da Ẹgbẹ awọn silẹ, oruko Ẹgbẹ na ni "The Nigerian Association Of Stockfish Importers." Ẹniti o ṣe Alaga Ẹgbẹ na ni Oloye J. A. Ajao, Ọtun Ọyọ, ẹniti iṣe asiwaju ninu iṣẹ onisowo panla, ninu ile rẹ ni 20 Egerton Road ni nwọn ṣe ipade akọkọ na.

Ninu ipade na, nwọn yan awọn enia mẹrin lati lọ joko ṣe igbimọ ki nwọn ro eto ati ofin ti o ba yẹ fun Ẹgbẹ na ki nwọn si mu ipinnu wọn wa si Ipade miran fun ayẹwo gbogbo Ẹgbẹ.

Nwọn si ṣe ipinnu pe ki nwọn ko ẹja panla ti ilu Norway (Norwegian Stockfish) silẹ ki nwọn ma ra a mọ fun igba diẹ tabi fun oṣu mẹfa, a fi bi nwọn ba dia owo rẹ ku, nitoripe awọn apedanu papọ lori ẹja ti nwọn ra lati ilu ibẹ, owo ti awọn ara ipo kọọkan lọhun ju iye owo ti awọn nta a ni lọ.

Lẹhin ti nwọn ṣe ipinnu yi tan ni nwọn ka ipade Ẹgbẹ na wa si ipari.

## IPADE APAPỌ IGBIMỌ-NLA BẸRẸ

Ni ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni Apapọ Igbimọ-Nla Asofin Nigeria bẹrẹ ipade ninu Ile Igbimọ Asofin Nigeria ti o wa ni Ọdan (Race Course Road) l'Eko.

Ki Ajọ Igbimọ na to bẹrẹ, ọpọlọpọ ero iworan ni o ti rogun si ita pẹlu idaraya ati ifarabalẹ, ṣugbọn awọn oho gẹẹ! Lọkọkan lati fi ṣamba awọn Asoju Igbimọ na ti nbọ de lọwọ lọwọ. Awọn Adajọ Agba wa nibẹ pẹlu ẹwu oye wọn ati Gbakeji Bisọpu Eko.

Lẹhin na ni Ọlọla John Macpherson Gomina Nigeria de, awọn ọlọpa si kọ orin "Ki Ọlọrun d'Ọba si" gbogbo awọn enia, awọn Asoju Igbimọ ati awọn ero iworan si nworan Gomina bi o ti nyan larin awọn Ṣọja ti o to lati ṣe ẹyẹ fun ọjọ ipade na.

Nigbati Gomina de ori ijoko idajọ Igbimọ Asofin na ni o ka pe alafia ati eto wa ni ilu ni ọdun ti o kọja a fi ilu bi meji ti nwọn ṣe gbolohun na) larin ara wọn.

O si tun menuka idatudapọ ti o bẹ silẹ ninu Igbimọ Asofin Ilu Ila Orun Nigeria pe ndsaiveja na le mu ifaṣẹhin wa fun ilu, o ni ṣugbọn awọn Irijẹ Igbimọ na ti mojuto ẹran na, ati pe gbogbo rẹ yio yi bọ si eto lapọ fun ire ilu Ila-Orun na ati fun anfani gbogbo ilu Nigeria.

O si sọ nipa aṣẹyọ ti Ijọba Nigeria yio ṣe nipa Ẹyẹ Igbade Ọba Oyinbo ti nwọn yio ṣe ninu oṣu kẹfa ọdun yi o, si ya ọjọ meji sọtọ fun isinmi Ajẹyọ na ọjọ ni iṣe keji ati ọjọ kẹta oṣu na, ọpọlọpọ ere ti yio wa, paapa fun awọn ọmọde awọn ti yio di ọlọla ilu lẹhin ọla.

Lẹhin na ni o ba awọn Asoju gbogbo sọrọ nipa atunṣe ti yio wa fun gbogbo ilu, nipa iṣẹ awọn alamojuto, nipa iye ti ilu Eko yio wa gẹgẹbi Olu ilu Nigeria. Atunṣe iṣẹ "Public Relation Department", atunṣe Ẹgbẹ awọn Ologun, atunṣe ọna

(Wo oju ewe kẹta)



Oloye J. A. Ajao
Ọtun Ọyọ ti o ṣe Alaga Ẹgbẹ Onisowo Ẹja Panla Nigeria ti nwọn da silẹ ni Eko



ỌLỌLA ỌBAFẸMI AWOLỌWO
O wa ninu Ipade ti nwọn nṣe lọwọlọwọ yi ninu Ajọ Apapọ Igbimọ-Nla Asofin Nigeria ṣe a daro a si ba iyi kun Ijọba. Gẹgẹ ti nwọn ba le fi han wa daju gbangba pe "OMINIRA ILU NIGERIA" yio bọ ninu ọdun 1956 ti gbogbo wa ti fi ọkan si.

## Awon Ọlosa Nsoro Ni Kano

KANO—Ọran ko dun ni iṣe ibi ti awọn Ọlọja npe ni Kano nibiyi, ni adugbo awọn Alejo ti a npe ni "Sabon Gari".

Nwọn pa Ebin Uwa Ikong Anita ọdọmọde-binrin ọlọtu mẹtadinlọgbọn ti nṣe iṣẹ olutọju alaisan (Nurse) ni ipẹ-ero ninu koso kan. Ko si ẹniti o le sọ bi awọn ti ṣe pa a sibẹ.

Nwọn fọle Ọgbẹni Adekunle ọkan awọn Onisowo U.A.C., nwọn si ko gbogbo dukia rẹ lọ. Bi o ti fẹ fi ija ko wọn lati gba diẹ pada ninu ẹru rẹ ni nwọn ba gun un l'ọbẹ lẹhin, awọn ni ti gbe Ọgbẹni na lọ si Ile Iwosan.

Lori gbogbo wahala awọn Ọlọpa, sibẹsibẹ na nwọn ko i ti ri mu ninu awọn Ọlọṣa na.

Ẹ MA A KA
IWE
Irohin Yoruba
Nigbẹ Gbogbo Fun
Irohin Aladun

